ROGBODIYAN BE SILE L'OKE - OYA



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


AWOGBA
Omode fun Girl, Eyl, Hiho-ehin, Orere.
Ra Tire Ni Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare Okebola, Ibadan.
116, Great Bridge St LAGOS

VOL. No. VIII 489. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, OCTOBER, 13, 1956. KOBO MEJI (2d.)

## Olopa si Omo'ba mu fun arufin

Ọlọpa ri awọn ẹnikan to parojọ sibi ti awọn enia meji ti nja, nigbati o ko awọn ti o nja tan o mu ọkan ninu awọn ọmọ ọba ilu na mọ wọn.

Wọn ko mọ ọmọba na, nigbati nwọn mu de Kotu nwọn 'bi lere ọrọ, ṣugb ọn ko fọhun, bẹni ọlọpa kan ba gba leti, sibẹ ko sọrọ. Nwọn ju awọn yoku silẹ ki nwọn ma lọ, ṣugbọn ẹniti nwọn bere ọrọ lọwọ rẹ ti ko dahun, nwọn lọ fi si itimọle.

Awọn ẹru ọba lọ sọ fun ọba pe nwọn ko ri ọmọ'ba yi ki o pada wa sile, nwọn rohin fun awọn ọlọpa, awọn na tun bẹrẹ si wa ọmọba yi.

Nigbati ọga ọlọpa lọ yẹ iṣẹ wo ti o ri ọmọba yi ni'timọle, ẹru ba a, o sare bere wipe nibo ni nwọn tiri ọmọba? ẹnikan si dahun pe, arufin ni.

Ọga ọlọpa ki gbe Ha! ọmọba, ti nwọn ti nwa? Nwọn ni ki nwọn lọ mu jade, ọmọba kọ lati jade, o nke'bosi wipe eti nro on, Oyinbo ọga ọlọpa wọle de, o bẹri fun ọmọba, o ṣa nke'bosi, wipe eti on, nwọn gba on leti o.

Nigbati ọlọpa ti o mu ọmọba na ri pe on gbe, lo ba bẹ sita, ni ọjọ kẹta ni ọlọpa ẹgbẹ rẹ ri mu nilu Sundam.

Oyinbo ọlọpa bere pe kili ọmọba fẹ ki a ṣe fun ọlọpa na, o dahun pe ki a fi silẹ, ṣugbọn ki nwọn fi ṣile marun kun owo rẹ, nitoripe ofin ko mọ ẹni ọwọ, ṣugbọn on ni ko ma wa sọ ẹnu ọna mi li ojojumọ. Owe, Bi yio ṣe emi tabi iwọ ni ko njẹ ki a yagbẹ s'oko alairoju.

**THE NATIONAL BANK**

**Of Nigeria Limited.**

Ile Ifi Owo pamosi yi
Nfi ona owo han eni
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
ran o lowo nipa wipe ao to o
si Ona ti o dara, ao la oju re
si Ona owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nse iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Duke of Edinburgh



Aworan oke yi niti ẹni-ọla, Ọlọlajulọ ọkọ Ọba obinrin ilu Oyinbo ti Ọlọlajulọ na pẹlu ẹrin'ojẹ-ọkọ-o na iyawo rẹ jọ jumọ wa bẹ ilu wa wo ninu ọdun yi.

Ẹni-ọla na yio kọja nilu Kano ni owurọ ọjọ Tuesday ọsẹ ti o mbọ nigbati o ba nlọ silu Mombasa lati lọ w'ọkọ ọla ti a npe ni Royal Yacht Britannia" ti yio mu lọ silu Australia lati lọ woran ere Olympic.

### ROGBODIYAN BẸ SILẸ L'OKE-ỌYA

Agbọju'gbanu irohin ti agbọ lati ilu Kano ilẹ awọn ọmọ alahusa ni w pe ko si ifọkanbale fuu awọn ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U. lasiko idibo yi, nitoripe ọpọlọpọ l'o ti fara ko'rin lai nidi pataki.

Ati wipe ẹnikan to ti dibo wọ'le ninu awọn ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U ni a gbọ pe o ti ku iku aburadi, nitori eyi ni Akonijẹ ẹgbẹ na ṣe kọwe si Ajẹlẹ agba, ki o ṣa iwadi nipa iku na.

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at:—
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge St
LAGOS.

## Ariyọ J'oba, Rikisi Pin

BADAGRY— Irohin ko to afojuba nibi ifijoye Ọba ilu Ibeshe labẹ Agbadarigi ni ọjọ ti Ọgbẹni Salu Ariyọ, ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) jẹ oye Ọba Ofori ti ilu Ibeshe.

Wọn ṣe eto ifijoye Ọba na gẹgẹbi aṣa ilẹ wa ni ọjọ kẹsan oṣu August 1956, laiko si ija tabi ariwo aburadi nibẹ rara. Ijo ati oriṣiriṣi ariya l'o gbojikan kakiri ilu ti olukuluku nṣe ti nwọn si nsọ. Irẹsi ko jẹ ki a mọ Amọla, bẹni iyan ko jẹ ki a mọ ọka gari. Ẹja tutu nsọ pọtọ, ẹran Malu npe onijẹ, ajẹti-mumuti ni ohun jijẹ ati ohun mimu l'ọjọ ifijoye na.

Nigbati o di alẹ ọjọ na ti awọn Ọlọpa Nigeria de si ilu Ibeshe, inu wọn dun wipe alafia ni nwọn ba ilu ti gbogbo nkan ndun yungba bi ẹni to ni 'adi mu'kọ. Ki a maṣe gbagbe lati sọ wipe nwọn jẹ Oye Balogun ati Balẹ ilu ni ọjọ na pẹlu.

Awọn ilu pataki to peju pesẹ sibi oye na ni ilu Ọjọ, Eko, Ilede, Iyagbe, Ibasa, Ilashe, Imọrẹ, Igbo, Igbologun, Ayimọranfide ati Ilado. Awọn enia pataki pataki to wa sibi jijẹ oye na le ni ẹgbẹrun enia.

Diẹ ninu awọn ti a le daruko ni Ọgbẹni Surakatu Eriwa, Lemọmu Jamiyu, Balogun Adini, Lemọmọ Surulere, Rufai Balẹ, Akanbi Ọlọja Buraimọ (Ọlori Killa) Bada Kansilọ, Dauda (Akọwe) Salu Badmus, Konigbagbe.

K'Ade pẹ l'ori, ki Bata pẹ l'ẹsẹ, o.

## Iwadi Oro Bank Azikiwe

OJUKWU BỌ SINU APOTI ẸRI

Ẹniti ọrọ iwadi tun kan ni Ọgbẹni Ojukwu ẹniti o ti fi igba kan nṣe olotu African Continental Banki, on kanna yi ni aṣoju olotu Eastern Region Marketing Board. O sọ wipe, bi awọn ẹgbẹ ti on wa ko ba ri ohun pataki kan ṣe fun anfani awọn enia ijọba ẹgbẹ na yio fọ.

Bi o ba jẹ wipe owo wa nilẹ ni, on iba sọ wipe ki a fi iwọn ẹdẹgbẹta ọkẹ poun sinu Banki na nitori ki a ba le ri owo ya awọn onisowo wa, fi owo ti npọn loju nitoripe Banki awọn oyinbo kọ lati ya awọn enia dudu lowo.

Nigbati emi pẹlu Zik bọ lati irin ajo wa lọ silu ọba, ati Amẹrika nijọsi, a ko fi ero ti Banki si ọkan rara, awọn aṣayan igbimọ Ila-orun lo mọ nipa ọrọ yẹn. Nipa iwe ti a ṣe lori bi ati rin irin ajo na si, eyiti a fi ranṣẹ si Gomina Ila-orun, emi pẹlu Azikiwe lojijọ ṣe iwe na, ṣugbọn Azikiwe lo kọ iwe na. Pataki ninu ọrọ rẹ nipe, ki ijọba ma ran enia dudu lọwọ.

Ojukwu sọ pe, on fi ẹnu sọ fun ọgbẹni Blackson lẹhinna ni on tun kọ niwe wipe, ki o ya awọn ile iṣẹ ti Azikiwe da silẹ ni ọkẹ mẹwa pọun, ki nwọn le fi wa ilọsiwaju ki nwọn si gba iru awọn to ba mọ iṣẹ na daju-daju On mọ wipe bi adanu ba de lori iṣẹ na, on mọ pe Zik ni ilẹ nla kan ni Onistha ati ni Nsukka, bi on ba ta ilẹ mejeji yi on yio ri owo ti on gba pada.

koiti pari

## Igbimo meji gba ara won leti

ỌYỌ. Ọrọ kan lo ṣe bi ọrọ larin awọn igbimọ meji, eyiti o dogun ohun ti ẹnikini fi ni lati dide lọ gba ẹnikeji leti nitori ọrọ ẹsin.

Ohun ti nwọn nṣe igbimọ le lori ni ọrọ nipa Mọṣalaṣi Jimọ wipe ọna kanṣoṣo lo yẹ ki nwọn ma kirun Jimọ. Ọrọ yi fa ibinu jade fun tọtun tosi tobẹ ti ẹnikan fi dide kuro ni ipo rẹ lati lọ gba ẹnikeji leti.

Lẹsẹ kanna, gbimọ daru, olukuluku si mu ọra silẹ lati ja, ọpẹlọpẹ awọn ọlọpa ti o mbẹ nitosi, awọn lo pẹtu si ọrọ na, ti ko jeki ijagboro tun ṣẹlẹ nigba keji l'Ọyọ.

Awọn onija mejeji yi jẹ ijoye ninu awọn ẹgbẹ oṣelu Afẹnifẹre ati ẹgbẹ N. C. N. C.

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ọfe


## IRIN AJO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ rin irin ajo, yala lẹnu iṣẹ tabi fun faaji lọ si ibikibi ni apa ilẹ Nigeria, tabi lọ si apa ilẹ Iwọ-Orun Afrika tabi lọ si ibikibi kakiri agbaiye.

WA BERE

Lọdọ awọn AMỌNA irin ajo yala lori omi, l'ofurufu tabi lori ilẹ ninu ọkọ Reluwe

Jẹki a ba ọ ṣe gbogbo wahala rẹ nipa Iwe aṣẹ fun irin ajo (Passports) Iwe Ọkọ-ilẹ (Tickets) aye ijoko si ati ifọkanbalẹ jamba (Insurance).

Ao ba ero Mẹka ṣeto Ọkọ pẹlu irọrun. Iranṣẹ ni ajẹ fun ọ lo wa.

**West African Travel Agency Co.,**
9, Victoria Street, Box 581,
LAGOS PHONE 23237


## AKIYESI

## Ile Awon Osise

Ati fi awọn oṣiṣẹ ti owo oṣu wọn de Ọdunrun poun l'ọdun kan kun awọn ti wọn le gba ninu awọn ile ti a nkọ fun awọn Oṣiṣẹ (Lagos Housing Scheme) ni ọna bayi:-

1. Nwọn ni lati gba odidi ile kan, ti o ni yara mẹta tabi mẹrin (iyẹn a awọn ile to ni yara meji-meji, ti a ti pese silẹ fun awọn oṣiṣẹ ti iye owo ti nwọn ngba l'ọdun kan, ko to ọgọrun Pọun.
   Awọn ti o ba fẹ gba ilẹ ti o ni yara mẹta ni lati ni enia mẹrin pẹlu ọmọde kan, ko ma si pọju enia mẹfa lọ. Awọn ti o ba fẹ gba ile ti o ni yara mẹrin, ni lati ni awọn enia mẹfa ati ọmọde kan, ko ma si pọju enia mẹjọ ati ọmọde kan lọ.
   Awọn ọmọde ti ko to ọmọ ọdun mẹwa ni a pe ni idaji. Ohun ti a npe ni ẹbi kan, oluwarẹ, iyawo ati awọn ọmọ rẹ.

2. Ẹniti o nfẹ gba ile titun ni lati jẹ ẹniti o ti ngbe Eko ni iwọn ọdun mẹwa sẹhin.

   Ki nwọn si jẹ ẹniti o wa labẹ yin bo kanna lati iwọn ọdun marun sẹhin.

Ẹniti o ba ni awọn ohun ti a daruko loke nwọnyi le ni aṣẹ lati bere ile titun. ao si ṣe iwadi awọn ohun nwọnyi kinni-kinni ẹniti ọrọ tirẹ ko bajẹ bẹ, ao fa iwe rẹ ya.

Ẹniti o ba fẹ gba ile titun na, ki o lọ gba iwe ti a fi mbere lọfẹ lọdọ L.E.D.B. ni Oko-awo tabi nibi nwọnyi:—

Ile Post Office ni Ẹhingbẹti,
Broad St.,
Apapa
Ebute-Metta
Yaba.

Ẹniti o nfẹ gba ile titun na yio da iwe rẹ pada sọdọ L.E.D.B. funra rẹ larin agogo mẹrin abọ irọle si agogo mẹfa abọ aṣalẹ, lati ibẹrẹ ọjọ Monday 15th oṣu Oct. si ọjọ 19th 1956. Ẹnikẹni ti o ba pọ lẹhin ki o to mu iwe tirẹ wa, lẹhin agogo mẹfa abọ aṣalẹ ọjọ 19th October 1956, a ko ni gba iwe na lọwọ rẹ.

ỌSẸ KAN NI A O FI GBA IWE NA, LARIN ỌJỌ 15th TITI DI 19th OṢU OCTOBER, 1956.

T. F. BARKER
Chief Administrative Officer.

## Ijoba fe bere si se Sugar nile Nigeria

Ọgbẹni A. C. Barnes C M G B. Sc, (Hono) F.R. I. C., A.M.I Chem. E ni alejo pataki kan ti ijọba Eko ranṣẹ pe, lati wa wo ilẹ wo lọjọ 13th oṣu Oct 1959.

Ohun pataki ti o titori rẹ wa ni wipe bi ilẹ yi yio ba rọrun lati bẹrẹ iṣẹ Ṣugar ṣiṣe,Ọgbẹni na jẹ ọkan ninu awọn olotu ile Iṣẹ Ṣugar ti a npe ni Tate and Lyle Technical Services Ltd.

Ọsẹ mẹfa ni yio fi wadi, yio lọ ¦si ilẹ Hausa ile Yoruba ati ile Ibo yio si tun lo si gbogbo ilẹ ¦Nigeria kari kari titi de Kamerun.

Lẹhin ti o ba pari iwadi rẹ tan, yio mu irohin pada lọ sile.

## Iye Awon Omo Ti A Bi L'eko

Bi ilẹ ti nṣu, ti o si nmọ bẹni awọn ara ọrun ntọwọ wa sile aiye.

Niwọn ọdun •1910 bi nwọn ba sọ wipe adọta ọmọ ni nwọn bi nilu Eko larin ọsẹ kan, nṣe ni a o ma ke Safula wipe nwọn ma bimọ pupọ. Bi nwọn ba si tun wipe igba enia lo re ọrun, a o ma wipe, ẹni t'o ku ko pọ.

Ninu ọsẹ to pari lọ yi 29th oṣu Sept iye awọn ọmọ ti a bi larin ọsẹ kan nilu Eko jẹ ọmọ marundilogoji le lọdunrun ṣugbọn iye awọn enia to kọja si ọrun alakeji are-mabọ, jẹ adọta pere.

Ile aiye minringindin ọrun ko ṣe gbe, awọn ọmọ Irumọlẹ, ati ọmọ oriṣa ko fẹ gbe ọrun mọ ile aiye ni nwọn sure bọ. Ha! ile aiye ndara.

## Abeke puro mo alaise

ABẸOKUTA. Irohin ta siwa leti pe Obinrin kan ti a npe ni Abẹkẹ l'oke Itoku lo lọ fi ẹjọ sun awọn ọlọpa wipe awọn ọlọṣa wa ko ẹru on lọ:

Ati pe awọn enia meji ti on fura si wipe o wa ji on lẹru na ko lọ ni awọn iyafin C. Ọkẹ, ati H. Kọsọkọ.

Nigbati awọn Ọlọpa fi ara bilẹ wadi ọrọ na, nwọn ri wipe irọ lo pa mọ wọn. Ohun ti o nṣe Abẹkẹ ni wipe, o raja awin lọdọ awọn Onisowo John Holt, owo yi adanu wọ inu rẹ o si jẹ gbese Poun mẹrindiladọta. Nigbati o ri pe on ko le ri san mọ, lo ba purọ mọ awọn ọrẹ rẹ. Ni adajọ ba sọpe ki o sare lọ gbin ẹwa loke Igbẹin.

## Olopa Mu Lemomu Iseyin

ỌYỌ Irohin ta si wa leti wipe awọn ọlọpa lọ lati ilu Ọyọ nwọn si lọ mu Lemọmu ilu isẹyin wa ti mọle.

Ohun ti a gbọ wipe Lemọmu na ṣe ni wipe, nigbati nwọn ṣe ẹjọ awọn to jijagboro ni Isẹyin, nwọn darukọ Lemọmu na, adajọ si paṣẹ pe ki awọn ọlọpa lọ mu alufa na wa.

Ijagboro na ni eyiti o ṣẹlẹ larin ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ni eṣi, odid ile mẹjọ ni nwọn dawo lulẹ ọpọ enia lo si fi ara pa.

Lemọmu na si wa ni itimọle

## Adie njefun arawon ko leriwo

ONITSHA. A gbọ irohin wipe igbimọ ibilẹ Alaṣẹ Onitsha ṣe ipade wipe, o yeki nwọn dawo jọ ki awọn fi ran Azikiwe lọwọ nipa inawo rẹ lori ọrọ ti nwọn nwadi lẹnu rẹ.

Ọrọ na da akiti yan silẹ larin awọn alejo. Awọn Alejo ti ko nṣe ọmọ ilu Onitsha fọn mu wipe, ko si ohun ti o le mu awon dawo fun Azikiwe, nitoripe, ọrọ ti nwọn nwadi lẹnu rẹ ọwọ ara rẹ ni, o si jẹ larin on ati Banki rẹ pẹlu Ijọba Gẹsi.

Ṣugbọn nigbati awọn ọmọ Onitsha fi dandan le pe, awọn yio dawo jọ lati fi ran lọwọ awọn ajeji dahun pe bi nwọn ba ṣe bẹ, awọn yio tu ija ti nwọn ti pari fun wọn pada. Onitsha Ibos Vs Non Onitsha Ibos.

## Gesi Nsana Ni Nwon Koja

Ọgbẹn Gaitskells lo sọrọ yi wipe nigbogbo ọrọ ti Antony Eden ti sọ lati owurọ wa ni on gbọ ni agbọye. Iwa ati iṣe Ọgbẹni yi fun ẹnikẹni laye lati rosu le ọrọ na lori, eyi ni ọrọ nipa ebute Suez.

O le jẹ otitọ wipe, ohun ti Ijọba ilẹ Egypt fe ṣe ni lati fi agbara gba ebute Suez yi, gẹgẹbi gbogbo wa ti mọ; ṣugbọn ọrọ ti a gbọ lẹnu Ọgbẹni Sir Anthony Eden lo nfi han wipe ijọba Gẹsi ko lero ija pẹlu Egypt, nṣe ni nwọn kan ṣana.

Ṣugbọn bi Egypt ba ṣẹṣi ta afọnja kan si wa, ọrọ na ko ni suwọn nilu Oyinbo. Iyẹn ni pe gbogbo adehun ti a ti jijọ ṣe ni Igbimọ gbogbo agbaiye ni a o ko, silẹ. Bi ẹnikan, bu si wa dan iru aṣa bayi wo nijọ miran, awa ni yio kọkọ ti oluwa rẹ lẹhin. Gbogbo awọn enia ti o mbẹ ninu Igbimọ Ijọba ho ge-e-e lẹkanna, nwọn si wipe maṣe bẹ, ma ṣe bẹ, maṣe bẹ.

polowo oja re si iwe irohin Eleti Ofe

Fun Alafia Ara ati Agbara Ninu Eje



HOMMEL'S
HÆMATOGEN

Lọ sọdọ awọn ti n nta egbogi Hommel's Haematogen l'oni, ki o si ra igo kan. Ki o ma lo nigba-gbogbo titi ti yio fi bẹrẹ si fun ọ ni agbara, nigbati yio ba fi to ọsẹ kan, awọn ọrẹ rẹ yio ri i, ati pe iwọ papa yio ri ayipada iyanu ninu alafia ara to njade ni oju rẹ.

FUN ỌMỌ TO NṢE AISAN TI O SI NRU

Onişegun Oyinbo sọ wipe egbogi Haemetogen dara fun iru ọmọ bẹ. O nfi ẹjẹ titun siwọn lara, laipẹ alafia ati agbara yio de si ọmọ na.

Ohun pataki ni egbogi yi jẹ fun awọn obi.



mbe ninu Iga fun tita ni Sabu egbogi kakiri ile Nigeria. Bere lodo Asoju wa:-
2, ALBAN PHARMACY LIMITED
Victoria Sueet, P. O. Box 461
LAGOS — NIGERIA.

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 489. LAGOS, SATURDAY OCT, 13, 1956.


## Imi eran nidi enia

Anjẹ ekuru ki o tan, a tun ngbọnwọ rẹ sinu awo. Kaka ko san lara iya ajẹ, o nfi gbogbo ọmọ rẹ bi obinrin, ẹiyẹ wa nkọlu ẹiyẹ. Owe meji nwọnyi li a fi ṣe ẹṣin ọrọ wa ninu iwe irohin ti ọsẹ yi, o jẹ nipa ohun ti o nṣẹlẹ loke Ọya lọwọ-lọwọ yi.

Bi awọn oṣelu ni apa Iwọ-orun ti nsa gbogbo agbara wọn lati gba Ominira fun gbogbo awa enia dudu awọn oṣelu kan lapa ọna Ariwa (Oke Ọya) nfẹ fi iṣoro si ọrọ na, gbogbo isọrọ ati ihuwasi awọn oṣelu Oke-Ọya, ko mu ifẹ ati ilọsiwaju wa fun wa gẹgẹbi orilẹ ede awa enia dudu.

Lẹnu ọjọ mẹta yi ni a gbọ wipe ijọba Ariwa ti ṣe ofin pe ọmọ ẹnikẹni ti o ba jẹ ara Ila-orun tabi ara Iwọ-orun, nwọn ko gbọdọ gba a silewe.

Bakanna ni ọkan ninu awọn olotu ijọba Oke-Ọya sọ wipe, ẹnikẹni ti o ba wa lati ilẹ Yoruba ati lati ilẹ Ibo, ki nwọn maṣe gba a si iṣẹ mọ nilẹ Hausa Họwu! mo ṣe bi ẹnyin Hausa na lo ma nsọ bayi wipe, Ganni, ganni agan araba dee dee. Nigbati ko si irufẹ ofin yi nilẹ Yoruba, kilofa a ti nwọn ṣe ofin yi nilẹ Hausa.

ANIKAN JỌPỌN

Bi o ba tilẹ jẹ wipe awọn olotu ilẹ Hausa fẹ jẹ anikanjọpọn, ti o jẹ pe ara wọn nikan ni nwọn mọ ọna ti nwọn ngba yi, ko tọ rara, nitoripe alawo dudu kanna ni wa. Bi a ba tẹle ti Pẹla, ijo na yio bajẹ. Ki owe na jẹ ti ẹnyin olotu ijọba wa.


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun onlruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

**MEDICINE STORES**

7, Egerton Road, Lagos


## Ilu Eko ko to si Adelabu

Ọlọla Gomina Robertson ti fi aṣẹ si wipe a ko tun le gba Malam Adegoke Adelabu si aye Minister Eko nibiti o ti wa ri, Şugbọn dipo rẹ, ijọba yan Ọgbẹni J. M. Johnson si aye na.

Adelabu ti wọle igbimọ Assembly, on lo si jẹ aşiwaju fun awọn Alatako ijọba ninu igbimọ na


IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opoiopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJ, ABO 2½d. FUN IGO KAN)
O wa Lọdọ:—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


## Alafin Egungun-oju Ati Awon Magba

Lati Ọwọ Ẹṣọ

Alafin Egungun-oju jẹ alagbara nigba aiye rẹ, o ni owo o si tun ni Ogun, ko si ẹru ohun ti o mba. Ni ọjọ kan awọn ọmọ awo Magba pe ara wọn jọ lati jiroro papọ lori ohun ti nwọn ko fẹ ti Ọba si nfẹ ṣe. Ọba fẹ fi Ogundeyi jẹ oye Alapini, Ogundeyi ẹwẹ si jẹ ẹnikan ti ko fẹran Magba tẹlẹ-tẹlẹ, eyi lo jẹki awọn Magba lodi si ifi joye rẹ.

Ẹniti o nşe Olori awọn Magba yi, awọn opitan sọ pe Oguudeyi lo lupa, awọn Magba wa binu wipe Ogundeyi ko ni jẹ oye na. Ogundeyi jẹ Ologun ni gba pupọ lo nşe iranlọwọ fun Alafin. Asẹhinwa-asẹhinbọ, Ọba dajọ lati fi Ogundeyi jẹ oye Alapinni.

Awọn Magba to mbẹ lọna oko gbogbo lo wa sile. Nigbati ilẹ ọjọ na mọ, ọsan di oru, ojo şu, o kanlẹ, o kan ọrun, Alafin ni fila kan, bi o ba ti de fila yi, bo ti wu ki ojo şu to, nşe ni yio folọ. Fila na da Alafin loju to ọşẹ Awujẹ. Nigbati awọn Magba gbọ wipe Ogundeyi nlọ si Afin, bẹni ojo si npọn, Alafin gbe fila rẹ de, ojo na si da, o wa ku aradun iyagbẹ, ọjọ na, ọrọ ko dun, bi Ogundeyi ti nlọ sile Ọba, bẹni aradun k ansọlẹ niwaju rẹ, o yara pada sile.

Titi ilẹ fi şu Ogundeyi ko le jade, Ọba papa ko ri awọn ijoye kankan. Inu wa bi Alafin, o ranşẹ si si awọn Magba wipe ki nwọn wa fi oju kan on, iye awọn ti o lọ to ọgọrun enia, ọba rope gbogbo wọn nuni. Nigbati nwọn de afin, ọba da wọn joko, o

(Wo y'oku loju ewe karun)

# Eto Titun Ilu Eko Se Ikilo

## Owo Iranlowo

1. Awọn onile ati awọn onisọbu lagbegbe apa ibiti ijọba ti gba, ti nwọn ko si ti fi iwe tiwọn ranşẹ si igbimọ L.E.D.B. fun owo iranlọwọ tiwọn, ki nwọn mọ wipe, ipari oşu Sept ni awọn ti nilati şe bẹ. (30th Sept 1956)

2. Nitoripe awọn apapọ ẹgbẹ ti o wa ni agbegbe ile wiwo da si ọrọ yi, on lo jẹki a tun sun ọjọ iwe na siwaju, bayi wipe :- Awọn ẹniti ko baiti fi iwe tiwọn ranşẹ, ki nwọn tete fi ranşẹ, ki o to to ọjọ 15th oşu Oct 1956.

3. A ko ni da ẹnikẹni ti o ba mu iwe wa lẹhin ọjọ kẹdogun oşu yi lohun.

4. Iru awọn ti ẹgbẹ oniranlọwọ nşe e fun, ni awọn (a) ti o gbojule owo ile wọn lati ma fi jẹun pẹlu enia wọn ti owo ti o nwọle fun wọn ko to mọ tabi (b) awọn onişowo ti a ti wo şọbu wọn lulẹ.

5. Nile işẹ awọn L.E.D.B. l'Oko-awo (Reclamation Road) ni a ti ngba iwe ti a fi mbere owo na lati agogo mẹjọ owurọ si agogo kan abọ ọsan.

**C.S. Clover**

**Alaga Ex-gratia Compensation Committee**

# FUN ARUN GEHIN-GEHIN Dan Egbogi Yi Wo



Bi arun gẹhingẹhin ba nyọ ọ lẹnu lasiko igbati o bẹrẹ tabi ti o nṣe nkan miran irora yio ma bẹ fun oluwa rẹ bi a ba si wadi rẹ ao ri pe ohun ti o fa a mbẹ lara Kidinrin tabi Ọlọ-inu, iṣẹ wọn ni lati tu gbogbo ororo ti ko dara kuro ninu ara ṣugbọn awọn Kidirin nwọnyi ko nsiṣẹ wọn daradara nigbamiran. Nitorina ẹhin ti o ndun ọ le jẹ ikilọ wipe Ọlọ-inu rẹ nfẹ iranlọwọ.

Egbogi ti o daju ti o le ṣiṣẹ yi ni DE WITT'S o nfọ idọti ara ẹni kuro o si ntu enia lara gbogbo awọn ti o ti nlo egbogi yi kakiri aiye lo ti nrohin rẹ.

Bi iwọ ba ka diẹ ninu iwe ti awọn ti o lo egbogi yi ti o ṣiṣẹ iwosan fun nipa ẹhin didun iwọ yio mọ daju wipe bakanna ni yio ma wo arun gẹhin-gẹhin tirẹ san Ese ti iwọ ko dan wo fun irora tirẹ boya yio jẹ ohun ti o ba ọ lara mu Bere ni Ṣọbu ti a nta egbogi.

A ṣe egbogi DE WITT'S nipataki fun arun GẸHIN-GẸHIN IGBA-ROKO, IWORA. ARUNGUN LAKUREGBE




Idaloju wa ni wipe egbogi DE-WITT'S jẹ eyiti a ṣe tonitoni ti ko si idọti kan lara rẹ.

**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**


# Alafin Egungun-oju ati awon Magba

(O bẹrẹ lọju ewe kẹrin)

wipe, bi ogun ko ba jẹ, on yio lo ọla on leri wọn, o si tilẹkun afin mọ wọn.

Ogundeyi wa dide lati da egbogi buruku si arin wọn nile ọba. Ki a to ṣẹju pẹ, ojo ti ṣu aradun ja, o jo ile Ogundeyi, o si jo ile Afin nibiti nwọn npe ni Bara. Ọna Iṣokun ati ọna Aka ba ọba damọran wipe ki o jẹki awọn Mọgba ma ni alafia nitoripe gbogbo wahala ti ọba nri yi Ogundeyi lo nko wa ba a. Ni ọba ba tu Magba silẹ pẹlu owo ati aṣọ ati ẹran.

Awọn Magba sọ fun Alafin wipe aiye ko le roju ayafi bi o ba fi ẹniti nwọn fẹ jẹ oye Alapini. Ọba bere tani nwọn fẹ nwọn si tọka Ọlawọye ọmọ Ẹgbẹji. Ọlawọye logunju ẹnikẹni lọ lode Ọyọ, on ni nwọn fi joye Alapini gẹgẹbi ifẹ awọn Magba, eyi ni nwọn npowe wipe, Bi ijimere ba foju kan Alapini, ọgbọn inu ẹ yio pin.

# Kilo pa won, omi ajalolo

IBADAN. Agbọ irohin bayi wipe, nile Alaisan ti Adeọyọ enia mejidilọgọrun lo gba ibẹ lọ si ọrun alakeji larin oṣu kan, Pantiwa?

Ninu awọn enia to ku wọayi awọn ọmọ ẹjẹ ọrun to wa ninu wọn jẹ mejidilo oji, awọn enia yoku jẹ ẹrude Ọlọrun.

A ọ[illegible] alaṣẹ ile iwosan na sọ wipe mẹtadilogun ninu awọn to ku na ni ijọba yio ṣe iwadi, iru omi ajalolo to pa wọn, ati iru kini aisan wọn na ati iru egbogi ti awọn lo fun wọn.

# Lemomu Iseyin jare

Bi a ti ntẹ iwe yi lọwọ l'agbọ wipe, Lemomu Iṣẹyin ko ba wọn l[illegible] ninu ijagboro o si ti pada lọ silu rẹ,


**Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS**

*Read this list of popular titles*

JZ 6037 – Bo Ba Sorun/Iya Egbe
" 6038 – Emi O Se Ola /Konkoji
" 6052 – Kusimilaya I / Yanbosa
" 6053 – Kilo Se E/Kusimilaya II

(Victor Olaiya & His Coo Cats Orchestra.)

" 6050 – The Gentleman in the Wardrobe / The Lady with the Pancake Make-up

(Bobby Benson & His Havana Orchestra)



" 6051 – Mamma Klapo / Uncle Joe

(Bobby Benson & His Havana Orchestra)

" 6048 – Erin Folami / Oju Lo Pesi

" 6049 – Egbe Mesho/Karimu Ajose

( isa Danbawa & His [Apala] Band )

*Sold by all the best stores*

HIS MASTER'S VOICE

**"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS**

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Die Ninu Awon Ohun Eriwo

Ko nşe gbogbo awọn ohun eriwo lo npa ri şugbọn wahala ati idamu owo lo nko wa ba ni. Pupọ ninu awọn enia na ko gba eriwọ gbọ. Ẹniti ko ba da loju ki o dan eyiti mo wi wo laşa.

1. Enia ko gbọdọ ji lorù ọganjọ ki orugbẹ ma gbẹ ẹ, ki o si lọ bu omi mu. Ẹniti o ba nşe bẹ oju yio bẹrẹ si yọ Oluwa rẹ lẹnu. Bi oluwa rẹ ba si sọ ọ di aşa tabi ma mumi loru oju oluwa rẹ yio fọ. Ọpọ enia lo siti ipasẹ eyiyi di afọju. Ẹrọ rẹ wa loto, fun awọn ti o ba ni lati lomi ni ọganjọ oru.
2. Aşọ titun, tabi aşọ elomiran ti iwọ ko fi kanra rẹ ri, şugbọn ti o wa di igba ti orun ti wọ, ti ile si ti şu tan ti o si la aşọ na bọrun tabi fi bora. Oluwa rẹ yio şe aisan nla kan bi ko ba baisan na lọ, yio fọwọ le itẹ ọrun. Awọn eni buruku lo nşaba lo iru eyi fun ẹniti nwọn ko fẹran. Bi otutu fẹrẹ ba mu enia, nwọn o yọ aşọ titun fun pe ko fi bora. Eyi ko dara.
3. A ko gbọdọ fọşọ lọjọ Saturday. Ẹniti o ba fọşọ lọjọ Saturday, bi oluwa rẹ ba şişẹ ko ni ri owo gba lasiko ti o fẹ, yio si şe jan a jan a lori asan, nigba pupọ ni yio ma şişẹ Samueli. Iru iwọnyi na ni ko njẹ ki alagbafọ la Tabi tal'o ri alagbafọ to lọ aşọ titi ti o di olowo ri?

## Enikan ku iku Aimodi

BUDAPEST. A gbọ irohin kan pe, ọkan ninu awọn Minister ilu yi, hu iwa idojuti, eyiti ko tọ ki a gbọ wipe, iru ẹni bẹ lo hu iru iwa bayi, ati ohun abuku lo jẹ fun ilu Budapest lati gbọ pe, iru iwa bawọnni ti ọwọ wọn jade wa.

Nwọn fi ẹjọ Minister na sun ijọba lọna ti o le mu ibinu wa, nwọn ba şe ẹjọ nwọn si dajọ wipe ki nwọn lọ yẹgi fun Minister na.

Lẹhin ọdun karun ti nwọn ti yẹgi fun Minister na tan, ni nwọn şẹşẹ wa ri ododo ọrọ na wipe, nwọn pa alaişẹ. Ha! nkan ti bajẹ, ko şe tunşe mọ, kini ohun ti awọn le şe lati fi wa idariji?

Nwọn tun şe igbimọ, nwọn wa pinnu bayi pe, ki nwọn lọ hu egungun ẹniti nwọn pa na, ki nwọn ko sinu posi, ki ijọba wa sinku rẹ pẹlu iyi, ati ẹyẹ.

Ọrọ Ọlọrun sọ pe, kili enia bi o ba padanu ẹmi rẹ, atunşe ko tun si mọ, ipade di alikiyamọ.

## Die ninu awon isami ati apere

1. Bi enia ba ri alantaknu lara ogiri lọsan gangan ọrọ ija kan yio şẹlẹ si oluwa rẹ kilẹ ọjọ na to şu. Şugbọn bi a ba pa a, ija na yio fo ni da.
2. Bi enia ba şakiyesi eiye Alapandẹdẹ ti nwọn nfo ni ibambalẹ, eyi jẹ ami pe, ojo ko ni pẹ rọ.
3. Bi enia ba nlo si ode ti o ba kọsẹ ọtun, yio ri ohun idunnu lọjọ na.
4. Bi imu ọtun ba ro enia gogo, oluwa rẹ yio ri iwe ayọ kan gba laipẹ.
5. Bi ẹniti o nwa işẹ ba şakiyesi pe ami ara nsọ on ni ejika ọtun, oluwa rẹ yio ri işẹ şe.
6. Bi agbari ba nyun enia nigba gbogbo, oluwa rẹ na yio l'owo laiye ki o to ku.
7. Bi agbẹdu ba yun enia, oluwa rẹ yio jẹ onjẹ ifa kan.


"*Ambitious people prepare for bigger incomes. The English Association of Accountants and Auditors. The English Association of Estate Agents and Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership by exemption (stat. professional experience) or Examination with Coaching by Correspondence College, Founded 1885. 9, Charles St., Newport, Mon. England*".


## Owe Yoruba.

1. Araiye l'okun
   Enia l'ọsa
   A o şe mọ iwẹ
   K'a to le k'aiye ja
2. Bi enia ba nyọlẹ da
   Ohun wẹrẹ-wẹrẹ a ma yọni şe
   Ẹni t'o ba gb'ebu ika
   Ọmọ rẹ a jẹ ni bẹ
3. Ọlọrun ko da kanyin-kanyin,
   K'o tobi bi ẹşin,
   A tapa ni iba ta ni,
   A tapa ni iba ta enia,
   Enia ti iba f'enia s'ẹsin
   Ọlọrun ọba kojẹ ki o nilari,
4. Bilẹ ngbe oşika,
   Ti ko gbe Olotitọ,
   Bi o ba pẹ titi,
   Ore a ma su'ni işe.
   Ile labọ isimi oko

Ajo ko le dun ki Odidẹ ma re Iwo
Lati ariwa si gusu
Ile labọ isimi oko
Digbolẹgun digbolẹgun
Laba-laba to digbolẹgun
Aşọ rẹ ni lati ya
Abamọ a si gbẹhin ọrọ rẹ.

Yẹkinni A[illegible]uta


# AKUFO IRIN.

## S. W. A. T: A.

NI ORUKỌ TI Ẹ MỌ TI Ẹ SI TI NGBỌ NI ỌJỌ PIPẸ, A O RA GBOGBO AWỌN IRIN TITUN ATI ALOKU, A o si san owo daradara. Ẹkanşoşo ni ẹ ba jẹ Onibara ẹ ko ni lofi wa silẹ mọ,

Ẹ o ri wa ni
50, King George Avenue, Yaba.
Phone. 44345.

AKIYESI:- A nta panu Fẹlẹfẹlẹ pẹlu o, Ẹnyin Alagbẹdẹ Alurin,






**Awon Elere Bolu Afesegba Feran**

**Siga Capstan**

**Orun Re Dara Pupo**



Aworan inu iwe wa yi ni ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin Elezabeth, nigbati o de Ade ti Saint Edward ti o si mu Abẹrẹ ati Igba'wa dani, nigbati o njade kuro ni Westminister Abbey lẹhin ti o ti gb'Ade tan.

Ẹ wo ogunlọgọ awọn enia ti o nwọ tirẹ lẹhin rẹ.

# Ole Ri Oloko O Jalule

IJẸBU Ode. A gbọ irohin wipe ọgbẹni onişowo ranpẹ kan file rẹ silẹ lọ si oko oloko lati lọ ji obi ka.

Ọgbẹni kan to wa jẹri fun ijọba sọ wipe, Ọkanrin ole na, nibiti ogbe nji obi ka ni Oloko de wa ba, o si bẹ lulẹ lati ori igi giga bi iwọn ọgbọn ẹsẹ, ibẹ ni o ti f'ara şeşe, a si gbọ pe, o şalaisi lẹhin na.

Ẹjọ ti agbọ wipe awọn ọlọpa mba Oloko na ro ni ẹjọ apania, ẹjọ na koiti pari, o si mbẹ ni kotu.





BENI! Hiho Ose Palmolive yio mu ara
RẸ RỌ YIO SI L'ẸWA

Ọşẹ Palmolive ko ntete tan, o to iye owo rẹ.

Epo pupa ni a fi şe ọşẹ na, yio mu ara rẹ tutu, yio si jọlọ.

Ilu Oyinbo lati mu Ọşẹ na wa, yio tu ẹ lara, ara rẹ yio ma dan.




Ose Palmolive nso enia di ajidewe


## IBERE

K ilohun to mbe l'apo ti ko si l'apo?
Ki l'Obo ti s'ori, Inaki kose?




# Iwadi Oro Banki - Zik

Ogbẹni Mackenna sọ fun Ojike wipe, on ṣe akiyesi ọrọ kan ninu iwe iranti ti nwọn gba lọwọ rẹ bayi pe se e A K B re Overdraft £500, wa ṣe itumọ ọrọ yi fun wa ki a gbọ.

Ojike dahun pe, nigbati on fi iṣẹ silẹ lọjọ 24th oṣu Jan 1956, ti nwọn ko fun on lowo iṣẹ on fun oṣu Feb ati March tobẹ ti ko fi si epinni aladọjọ lọwọ on mọ, nigbana mo gbero lati

Iye owo ti on ya ni ẹdẹgbẹta Pọun ati ele ori rẹ adọta Pọun, nitoripe ko si oniranlọwọ kan mọ.

Ojike ti kọkọ sọ wipe, on ba Azikiwe sọrọ wipe ki o jẹki awọn bẹrẹ si lọ fowo sinu Bank of British West Africa. Ṣugbọn Azikiwe dahun pe rara, bẹkọ awọn nilati bẹrẹ si fi owo sinu Continental Bank ti Enugu, ti Aba ati ti Onitsha.

Nigbati o di ọjọ keje



## Ogbeni Mbonu Ojike

lọ ri Ogbẹni A. K. Blankson ti o nṣe olotu African Continental Bank. Lati le ya mi ni ẹdẹgbẹta pọun. Ohun ti o jẹki o di tulasi fun mi lati lọ ya owo nigbana ni Iwadi ọrọ ti Ogbẹni Ikpeasu nṣe lasiko na ni Onitsha.

ti Ojike ti nsọrọ nibi iwadi ọrọ, ni nwọn to jọwọ rẹ lọwọ wipe ki o ma lọ. nṣe lo saragaga jade kuro ninu apoti ẹri, o si gbagbe Fountain pen rẹ sori apoti ẹri, ki nwọn to pe e pada lati wa mu.

# Kabo o, Oloye olola Enahoro.



ANTHONY ENAHORO

Oloye Tony Enahoro, ti o ti ba iṣẹ lọ silu ọba larapa awọn ohun ti o jẹ mọ iṣẹ rẹ, pada de si ilẹ Nigeria lọjọ Saturday oni yi 13th Oct. 1956.

Ohun ti o mu oloye yi lọ si irin ajo rẹ ni wipe, o lọ ṣe iwadi lọdọ awọn ti o wa ni iru aye ti on na wa gẹgẹbi nwọn ti ni lati ṣe iṣẹ wọn.

Nijẹta ni ọgbẹni Enahoro pe apejẹ nla rẹfẹlu kan nilu Oyinbo lọhun lati fi dagbere idupẹ fun awọn ti o ṣe iranlọwọ fun nipa awọn ohun ti o titori rẹ wa silu ọba.

Kabọ o, alafia kọ l'ẹ de bi?






No. 145.

# Vacancy For Manual Training

## Instructors At The Handicraft CENTRES EBUTE METTA

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to two vacant posts of Manual Training Instructor at the Handicraft Centres in the Ebute Metta Area.

Scale of salary: -

D1. 150 x 6 - 162 ; 180 x 9 - 198
2. 207 x 9 - 234 ; 246 , 258
3A. 294 x 12 - 318 ; 330 x 15 - 390; 408
(Randell's Report)

Qualifications:- Applicants should possess a Manual Training Instructor's Certificates awarded by Yaba Technical Institute on satisfactory completion of the two years course.

Duties:- The persons appointed will be posted to the Handicraft Centre, Ebute Metta. One vacancy is for Instructor to teach mainly metal work and the other mainly wood work to the upper Classes in the Senior Primary Schools of the Ebute Metta Area.

Other conditions of Service:-

1. The person appointed will be on probation on for three years.
2. The successful candidates will be expected to take up their appointments in - 1957.

Method of Application:- Applications should be addressed to the Cheif Education Officer, Lagos Education Office, Education Department, Lagos, so as to reach him not later than 30th November, 1956.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicant's Department and the Secretary of the Public Service Commission concerned and be accompanied by a Confindential Report on the Confidential Report Form.

# E k'abo o, Ero ilu Oyinbo

Ni ọjọ ọsẹ to kọja ni Oloye Ọbamuwagun tilu Ọwọ, Dokita S. O. Awoliyi ti ilu Oyinbo pada de si Eko ninu ọkọ M.V. Apapa to gunlẹ lọjọ ọsẹ (Sunday).

Dokita Awoliyi lọsi ilu Oyinbo ninu oṣu Febuary lati lọ tun kọ'ṣẹ-mọṣẹ, awọn Oloye meji l'o ti ilu Ọwọ wa pade rẹ ni Apapa gẹgẹbi aṣoju Ọba Ọlọwọ. Awọn enia pataki si pọ to wa pade Oloye Ọbamuwagun l'ori Kereni Apapa.

Diẹ ti aye wa lati darukọ ninu awọn enia to wa ni Dokita Bailey ati iyawo rẹ, awọn Ogbẹni M. Bank Anthony, J.F. Fakolujọ, S.B. Roberts, M.O. Idowu, T.F. Verrisimọ, Iyafin Ronkẹ Faderin ati Iyafin G. Macaulay.

Printed & Published by The ... printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23373